# IṢURA INU OKO; PERLI OLOWO IYEBIYE
# ÀWỌ̀N ẸJA
## Matteu 13:44-52
## ẸKỌ 78 FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI:“Ẹ ronupiwada; nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀” (Matteu 3:2).**

### Ẹtan Ọrọ̀

Wiwá iṣura ti o fara pamọ ti jẹ́ ilepa ọpọlọpọ eniyan lati igba de igba; itanjẹ ọrọ̀ ti o fara sin tabi ti iho ilẹ titun nibi ti a le ri wura, ti mu ki ọpọlọpọ eniyan kọ ẹbi ati awọn ọrẹ wọn silẹ, ki wọn ta ile, ki wọn jọwọ gbogbo nnkan ti wọn ni silẹ, ki wọn si la awọn iṣoro nla kọja – gbogbo eyi ṣẹlẹ bẹẹ ni ireti lati ko ọrọ̀ ayé yii jọ. Ọpọlọpọ ninu awọn eniyan wọnyii ni o ti ba ijatilẹ pade, ti ọwọ wọn kò si tẹ ohun ti ọkàn wọn n lepa. Ṣugbọn wò o bi ayọ̀ ati inu didun ti pọ to fun awọn eniyan ti wọn ti ri iṣura naa ti wọn n lepa, awọn ti wọn ti fi ọpọlọpọ nnkan jì lati wa ilẹ jin lọ sinu ajà ilẹ ti wọn si ti ri ọrọ̀ pupọ!

### Iṣura ti O Tobi Julọ

Jesu fi Ijọba Ọrun wé iṣura kan ti a fi pamọ sinu oko kan. Nigba ti ọkunrin kan ri i, o ta gbogbo nnkan ti o ni ki o ba le ra oko naa ki o si le gbadun iṣura ti a fi pamọ sibẹ. Iṣura yii ni Jesu ati Ihinrere Rẹ̀, otitọ ti a fi pamọ sinu Ọrọ Ọlọrun. Ẹlẹṣẹ ko le ni oye ayọ ti o wà ninu igbala, iṣura ti o wà ninu Ọrọ naa pamọ kuro loju rẹ̀. Ọkan ti o kun fun ẹṣẹ ko le ri ohun kan ti o dun mọ ọn ninu ni ọna iwa-mimọ; ṣugbọn nigba ti eniyan kan ba n fi tọkantọkan wá otitọ, oun yoo ri i ninu Ọrọ Ọlọrun. Kiakia ni yoo kọ gbogbo ohun aye silẹ ki o ba le ri iṣura yii: si wò o bi ayọ rẹ yoo ti pọ to nigba ti o ba mọ ayọ igbala jinlẹ ninu odò ọkàn rẹ̀!

Oluwa sọ ọrọ yii nipasẹ Sọlomọni, ọkunrin ti o ni ọgbọn julọ ni gbogbo ayé: “Ọmọ mi, bi iwọ ba fẹ igba ọ̀rọ mi, ki iwọ si pa ofin mi mọ́ pẹlu rẹ̀ … Ani bi iwọ ba nke tọ̀ ìmọ lẹhin, ti iwọ si gbé ohùn rẹ soke fun oye: bi iwọ ba ṣafẹri rẹ̀ bi fadaka, ti iwọ si nwá a kiri bi iṣura ti a pamọ́, nigbana ni iwọ o mọ̀ ibẹ̀ru OLUWA, iwọ o si ri imọ Ọlọrun” (Owe 2:1-5).

Awọn ẹlomiran ri i pe owo nikan ko le fun wọn ni ayọ, ṣugbọn wọn ro pe kikọ́ ẹ̀kọ́, ririn irin-ajo, wiwà ni ipo ailewu, ati wiwa laaarin ẹgbẹ ayé yoo mu ki ayé wọn kun fun itẹlọrun; ṣugbọn ọgbọn ayé yii, nini ohun ini ni anito ati wiwà lai bẹru, ohun ti awọn eniyan n pe ni “awọn ohun ti o sàn ju ni aye”, ko jamọ nnkan kan lai ni Jesu. Ninu Rẹ̀ ni “a ti fi gbogbo iṣura ọgbọ́n ati ti imọ pamọ́ si” (Kolosse 2:3).

### Niniyelori Awọn Ohun Ọṣọ

Ilepa ọ̀ṣọ́ iyebiye tun jẹ ohun ti ọpọlọpọ eniyan tun n sare si lori ilẹ ati lori okun. Bi ohun ọṣọ naa ba ti ṣọwọn to, bẹẹ ni yoo ṣe niye lori to. Ẹgbẹẹgbẹrun aimoye naira ni a ti san fun diamọndi kan, eyi ti ko le mu ayọ ti o pẹ lọ titi wa fun ẹni ti o ni in. Nigba ti awọn ọjọgbọn ninu ọna bẹẹ ba gbọ nipa ohun ọ̀ṣọ́ olowo iyebiye kan, o le ra a bi o ba ni owo tó; o dabi ọkunrin naa ti Jesu n sọ nipa rẹ pe o gbọ nipa perli olowo iyebiye, ti o si ta gbogbo perli ti o ni ki o ba le ra eyi ti o niye lori julọ.

### Jesu ni Perli Wa

Jesu fi iru iṣẹlẹ bayii ṣapejuwe ohun ti o n ṣẹlẹ nigba ti ododo Ihinrere ba di mimọ̀ fun eniyan. O ti gbiyanju lati ni gbogbo awọn ohun itura ati giga ninu ayé yii, ṣugbọn ko ni itẹlọrun titi o fi gba Kristi ni Olugbala rẹ̀, Ẹni ti O wá lati rà a pada. Jesu ni ohun ti o niye lori julọ fun wa; Jesu kú lati gba ẹlẹṣẹ là, lati mu wọn wà ni imurasilẹ fun Ọrun. O ṣe ọ̀wọ́n ni ọna titayọ, “Nitori kò si orukọ miran labẹ ọrun ti a fifunni ninu enia, nipa eyiti a le fi gbà wa là” (Iṣe Awọn Apọsteli 4:12). Oun ki i ṣe perli olowo iyebiye kan lasan, ṣugbọn Oun nikan ṣoṣo ni O niye lori lọpọlọpọ bẹẹ. Bi a ko ba mọ riri bi Oun ti niye lori to fun wa, bi a ko ba jọwọ ohun gbogbo silẹ, a ko ni le lọ si Ọrun.

Paulu Apọsteli woye pe ìyè a maa ti ipasẹ Jesu nikan wa, oun si jẹ ẹni kan ti o ta gbogbo ohun ti o ni, ki o ba le ni Jesu. O wi bayii pe, “Nitõtọ laiṣe ani-ani mo si kà ohun gbogbo si òfo nitori itayọ ìmọ Kristi Jesu Oluwa mi: nitori ẹniti mo ti ṣòfo ohun gbogbo, mo si kà wọn si igbẹ́, ki emi ki o le jère Kristi” (Filippi 3:8).

### Iyebiye fun Awọn Onigbagbọ

Ta ni ẹni ti o ri Jesu bi Ẹni ti O ṣe iyebiye? “Nitorina fun ẹnyin ti o gbagbọ́, ọla ni: ṣugbọn fun awọn ti kò gbagbọ́, okuta ti awọn ọmọle kọ̀ silẹ, on na li o di pàtaki igunle” (1 Peteru 2:7).

Bawo ni a ṣe le “ra” Jesu? A ko le fi owo ra igbala wa. Isaiah wi pe: “Njẹ gbogbo ẹniti ongbẹ ngbẹ, ẹ wá sibi omi, ati ẹniti kò li owo; ẹ wá, ẹ rà, ki ẹ si jẹ; lõtọ, ẹ wá, ẹ rà ọti waini ati wàra, laini owo ati laidiyele” (Isaiah 55:1). O n fi Ihinrere wé ounjẹ ati ohun mimu, awọn ohun ti n mu eniyan wà laaye: o n gbiyanju lati fihàn pe a le ri ohun ti ẹmi gbà lai fi owo rà a.

**Kíkọ Gbogbo Rẹ̀ Silẹ**

Ki ni ohun naa wayii ti a n beere lọwọ wa? A le "ra" awọn ohun ti Ọrun nipa kikọ ẹ̀ṣẹ wa silẹ, nipa jijọwọ ohunkohun silẹ ti o le di wa lọwọ lati gbé igbesi-ayé wa fun Jesu ati lati sin In pẹlu gbogbo àya wa. Peteru sọ fun Jesu pe oun ati awọn ọmọ-ẹyin iyoku ti fi gbogbo rẹ̀ silẹ lati tẹle E. Jesu si dahun, "Lõtọ ni mo wi fun nyin, Kò si ẹniti o fi ile, tabi aya, tabi ará, tabi obi, tabi ọmọ silẹ, nitori ijọba Ọlọrun, ti kì yio gba ilọpo pipọ si i li aiye yi, ati li aiye ti mbọ̀ ìye ainipẹkun" (Luku 18:29, 30). Nigba miiran Oluwa sọ fun awọn eniyan "Gẹgẹ bẽni, ẹnikẹni ti o wù ki o ṣe ninu nyin, ti kò ba kọ̀ ohun gbogbo ti o ni silẹ, kò le ṣe ọmọ-ẹhin mi" (Luku 14:33).

Igba pupọ ni a maa n sọrọ nipa sisan ohun ti Ihinrere yoo gbà wá. Ohun ti yoo gbà wa ni jijọwọ ifẹ inu wa silẹ patapata fun Jesu, to bẹẹ ti Oun yoo fi le sọ fun wa pe ki a ṣe ohunkohun ti O ba fẹ, ki a si ṣe e.

**Àwọ̀n Ẹja**

Jesu tun pa owe miiran nipa Ijọba Ọrun. O fi Ijọba naa wé àwọ̀n ẹja ti a sọ sinu omi, nigba ti a si fa a soke oriṣiriṣi ẹja ni a ri ninu rẹ, ati rere ati buburu. Ṣugbọn apẹja naa ko fẹ awọn ẹja ti ko dara fun jijẹ, nitori naa o yà wọ́n sọtọ kuro lara awọn ti o dara, o si kó wọn danu.

Awọn eniyan rere ati awọn eniyan buburu ni lati maa gbé pọ nisisiyii, ṣugbọn nigba ti Jesu ba pada de si ayé yii yoo mu awọn ti Rẹ̀ lọ lati maa ba A gbe, ṣugbọn awọn eniyan buburu ni Oun yoo sọ sinu iná ainipẹkun nibi ti ijiya nlá nlà yoo gbe wa, to bẹẹ ti awọn eniyan yoo maa gbin ti wọn yoo si maa pa eyin keke. Ko yẹ ki ẹnikẹni lọ si ibi buburu yii. Olukuluku wa ni o le wà laaarin awọn ẹja rere ti Jesu fẹran, bi a ba fẹran Rẹ̀ to bẹẹ ti a fi n gbe igbesi-ayé wa gẹgẹ bi O ti n fẹ.

**Iṣura Titun ati Ogbologbo**

Jesu beere bi oye awọn owe ti Oun pa ba ye wọn. Wọn dahun pe: "Bẽni, Oluwa." Otitọ ti o ṣe iyebiye ni awọn nnkan wọnyii ti Jesu n fihan awọn eniyan Rẹ̀, O si n fẹ ki wọn sọ fun awọn ẹlomiran. Awọn akọwe ni awọn ti o le ka Ọrọ Ọlọrun ki wọn si ṣe alaye rẹ̀. Jesu n fẹ ki awọn eniyan Rẹ̀ jẹ awọn akọwe ti o ni oye igba oore-ọfẹ ti Oun n waasu rẹ̀, ki wọn si le ṣe alaye fun awọn eniyan miiran. Ko si ohun ti o ṣe iyebiye bi Ihinrere.

Ohun ayọ ni o jẹ fun Onigbagbọ tootọ lati sọ nipa ohun ti Jesu ṣe fun un. Boya, ọpọlọpọ ọdun sẹyin ni a ti gba ọkàn rẹ̀ là, ṣugbọn ibukun pupọ ni ó tun n ri gbà sibẹ lati sọ nipa bi Ẹmi Ọlọrun ti pe e lati tẹle Oluwa. Ọlẹ̀ ayọ a maa sọ ninu ọkàn rẹ̀ nigba ti o ba n ro ọna iyanu ti a gba lati ṣe itọni oun titi o fi de ibi ti o le gbọ itan oore-ọfẹ ti n ra eniyan pada. Eyi jẹ "iṣura ti laelae." Ṣugbọn Onigbagbọ ko ṣẹṣẹ ni lati boju wo ẹyin, wo ohun ti ọpọlọpọ ọdun sẹyin ki o to mọ bi Ihinrere ti jẹ ohun ti o niye lori to ninu igbesi ayé rẹ̀. Ojoojumọ ni o n ri iṣura titun; ifarahan Ọlọrun ojoojumọ a maa sọ agbara rẹ̀ di ọtun a si maa fun un ni ayọ lọtun, o si n fẹ ki ayé ki o mọ̀ nipa rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni iṣura wa ti a fi pamọ?
2. Ki ni ọkunrin ti o ri perli olowo iyebiye naa ṣe?
3. Ki ni a ni lati ṣe lati ri igbala ki a si ni Jesu ninu ọkàn wa?
4. Awọn wo ni Jesu fi ẹja rere ati ẹja buburu ti o wà ninu àwọ̀n ṣe akawe rẹ̀?
5. Bawo ni yoo ti pẹ to ti gbogbo wọn yoo fi wà pọ̀?
6. Ki ni awọn "iṣura wa laelae ati titun?"